# Kòsí ijọkan ti wọn yóò dide láti ibi jokolẹ kan láì dárúkọ Ọlọhun níbẹ ayaafi ki wọn didi bi àpèjúwe okunbete Kẹtẹkẹtẹ, bẹẹ ni yóò tún jẹ ìbànújẹ́ fún wọn

Lati ọdọ Abu Hurayrah - ki Ọlọhun yọnu si i - o sọ pe: Ojiṣẹ Ọlọhun (ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a) sọ pe: "Kòsí ijọkan ti wọn yóò dide láti ibi jokolẹ kan láì dárúkọ Ọlọhun níbẹ ayaafi ki wọn didi bi àpèjúwe okunbete Kẹtẹkẹtẹ, bẹẹ ni yóò tún jẹ ìbànújẹ́ fún wọn.
[O ni alaafia] [Abu Daud ni o gba a wa]

Anọbi (ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ máa ba a) fún wa niro pe kò ní sí awọn apapọ eniyan kan tí wọn joko sí ààyè ijoko kan ti wọn wa dìde láì dárúkọ Ọlọhun nibẹ àyàafi ki wọn dide gẹgẹ bí àwọn ti wọn ko jọ lórí òku kẹtẹkẹtẹ ni ori akitan ati aye oorùn; eleyi ri bẹ nítorípé wọn ṣe airoju kuro nibi ìrántí Ọlọhun, ijoko naa yoo jẹ ìbànújẹ́ fun wọn lọjọ igbende, yoo si jẹ abuku ati àbámọ ti yóò maa wà pẹlu wọn.



النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee